# ATOKA ORI ORO


| | Akoko | Oju Ewe |
|---|---|---|
| **Iha Gusu Ile Afirika dojuko Ewu Ajalu Ojiji lori Arun Kogbogun AIDS**<br>*O to adota egberun omo iha gusu ile Afirika to nni arun kogboogun AIDS lososu* | 1min 45secs | 7 |
| **Ile Afirika dojuko ewu airiounjeje**<br>*Ogun abele ati awon kokoro ajeireoko ti jeki o soro fun opolopo omo ile Afirika lati bo ara won* | 1min 37secs | 4 |
| ORO AJE ATI IGBE AYE<br>**Isaretobisi awon ilu ntesiwaju ni ile Afirika**<br>*Awon ilu ile Afirika nsare tobi ju iwontunwonsi fun agbaye lo* | 21secs | 14 |
| **Ile Afirika polongo anfani idoko-owo to wa ninu re**<br>*Ile Afirika ngbaradi lati fa awon oludoko owo nlanla ni agbaye mora* | 2mins 48secs | 8 |
| EKO<br>**Alafo laarin iforukosile okunrin ati obinrin ni ile-eko ni ile Afirika**<br>*Opo awon omodekunrin ni a nfi oruko won sile ni ile eko ni opolopo orile-ede ile Afirika ju awon omodebirin lo* | 46secs | 13 |
| ILERA<br>**Egbogi titun ndabobo awon omo ikoko awon iya to ni arun kogboogun AIDS**<br>*Egbogi titun ti awon omo orile-ede Uganda ati America gbe dide ni o fi ireti fun iran ile Afirika to mbo* | 1min 32secs | 7 |
| ORO AWON OBINRIN<br>**Opo ninu awon obinrin orile ede Sudan lo wa logba ewon**<br>*Owo ninu oti lile nfi egbegberun awon obinrin iha gusu orile-ede Sudan sinu ogba ewon lododun* | 1min. 53secs | 6 |
| AYIKA<br>ITOJU<br>**Oro to enikan so lori Itoju: Ipadanu Ipinsiyeleyele awon eweko ati eranko**<br>*Iwa omugo iran yi ti yio soro fun awon iran wa ti mbo lati fori re ji wa.* | 34secs | 14 |

**Ati se afihan ilana lati dabobo awon odo ile Europe** 1min 11secs 5
*Ajo WWF gbe igbese lati dabobo awon odo adayeba ti ile Europe*

**Orile-ede Canada se pataki si Ipinsiyeleyele awon eweko ati eranko** 26secs 14
*Bi idamewa gbogbo igbo agbaye lo wa ni orile-ede Canada*

**Idaamu lori Omi Mimo** 14secs 13
*Yio fere to okan ninu awon orile-ede meta ti yio se alaini omi mimo to laarin adota odun si*

OUNJE

**Opo Iresi sii pelu omi ti ko to ti tele** 2min 34secs 9
*Isaredinku omi agbaye ti fi ogbin iresi sinu ewu. Awon onimo ijinle sayensi nwa ona lati fi lo omi to kere ju ti ateyinwalo*

**Erekusu Zanzibar gbesele eja lati inu adagun** 1min 50secs 5
*Ifurasi wipe awon ogun ipakokoropaeku ti tu sinu awon adagun nlanla ti iha ila oorun Afirika ti mu ki awon olura keyin si awon eja awon odo na*

AWON AGBEGBE TI A DABOBO

**Orile-ede Naijiria polongo awon ogba egan orile-ede titun** 51secs 4
*Awon ibudo aabo meji fun awon eda abemi egan di ogba orile-ede*

IMO NIPA ISE ONA

**Awon oko inu ofurufu ayiayepo le sotele lori ibesile iba oloro** 2mins 7secs 10
*Awon Akosile oko inu ofurufu ayiayepo le se iranwo lati dabobo awon eran-osin kuro lowo arun apani*

EDA ABEMI EGAN

**Eye to nso agogo** 59secs 14
*Iseda Aye si aso loju iyanu kan ninu egan orile-ede Indonesia*

ETO AWON OMODE

**Kiniun at Eku** 2mins 3secs 11
*Eni ba dami siwaju yio tele tutu*

**Kini idi re ti awon Adan fi nfo lale?** 1min 5secs 11
*Awon adan le riran daradara lale*

| | | |
|---|---|---|
| **Iwa odaran to buru jai ti ehoro to nje Kadima hu**<br>*Mo idi ti awon abo amotekun se ndanikan se ode ati idi ti ehoro ti aya e ba ja fi nsure laibojuweyin* | 4min 10secs | 12 |
| **Orile-ede Itali gboro nipa iwa odaran lori ayika**<br>*Orile Itali fi ipinnu re han lati da didanasun awon ogba egan orile ede duro* | 44secs | 13 |

# Iroyin

**Ile Afirika dojuko ewu Airounjeje 1min. 37secs**

Oju milionu (egberun lona egberun) mewa eniyan ni awon orile-ede ile Afirika merindinlogun to nfe iranlowo ounje ni kiakia lati le yera fun irokeke airiounjeje. A mo eyi lati inu ifitonileti ti Ajo Agbaye fun oro Ounje ati Ise Ogbin (UN Food and Agricultural Organization (FAO) to wa ni ilu Rome gbe jade laipe yi.

Gegebi oro FAO ni ojo kerindinlogun osu kejo odun yi: “ogun abele, ogbele ati awon kokoro ajeireoko ti se idilowo fun ipese ounje ni iha isale asale Sahara ni ile Afirika nibiti irokeke ewu airiounjeje ti wa fun ogororun egberun eniyan.

Orile-ede Angola ni owongogo ounje na kan julo. Amoye agba lori oro aje fun FAO, Mwita Rukandema, so wipe ogun abele to be sile laipe yi ti jeki ikowole iranlowo ounje di ohun eti ni Angola. Nse ni awon egbe ogun Egbe Ajumose fun Ominira Patapata fun orile-ede Angola (Union for the Total Independence of Angola (UNITA) nfi pelepele le awon eniyan kuro ni ile won. Awon egbe ogun na nge titi, won nda awon oko lona, won si nyin agba lu awon ilu. Gegebi afikun Rukandema: “Bi eleyi ba tesiwaju fun osu meji si, a o gbo awon iroyin airounjeje to buru jai fun opolopo eniyan.

Rukandema so wipe ona kansoso ti a le fi yera fun ajalu yi ni lati parowa fun awon omo ogun ijoba ati ti awon olote lati fi aye sile ni oju ofurufu. Iwonba ibudo oko ofurufu die ni baalu to ngbe iranlowo bo ti le bale nisisiyi, ounje ati egbogi ti won si nle gbe wa ko to. Opo awon omo orile-ede Angola ati omo ile-okeere osise aanu to ntiraka lati gbe ounje wolu ni won ti padanu emi won ninu awon idana ti a gbo pe awon olote se.

*Africa News On Line.*

**Orile-ede Naijiria polongo awon ogba egan orile-ede titun 51secs**

Ni ojo keta osu kejo odun yi, ijoba orile-ede Naijiria so Ibudo Aabo Eda Abemi Egun ti Okomu ni iha gusu Naijiria ati Egan Iyasoto Awon Eran-ode ti Kamiku (iha ariwa Naijiria) di awon ogba egan orile-ede titun ni orile-ede na.

Ibudo Aabo Eda Abemi Egan ti Okomu ni a da sile ni nkan bi odun medogun seyin ni Igbo Iyasoto ti Okomu to je akokose ise agbese ti Ajo Afenifere fun Itoju Ayika ati Iseda Aye ni orile-ede Naijiria (Nigerian Conservation Foundation (NCF) to je alabasisepo ajo kariaye fun itoju, iyen Ajo Akojo Owo fun Iseda Aye (Worldwide Fund for Nature (WWF). Ogba egan na ti o je ibuso kilomita mejileladofa ni igun mererin re ni o je ibudo isinmi fun awon eye to nsi kiri ati ile fun orisirisi eda abemi egan lara eyiti a ti ri erin igbo ati obo olorunfunfun.

Gegebi Alhaji Lawan Marguba to je oludari ajo olutoju awon ogba egan orile-ede se so: “Eyi je idagbasoke to dara fun orle-ede wa”

*Paddy Ezeala/WWF*

**Erekusu Zanzibar gbesele Eja lati inu adagun 1min 50 secs**

Erekusu Zanzibar ti gbesele iko eja wole lati adagun Victoria ni osu meje leyin ti apapo ile Europe na gbesele iko eja wole lati ekun na latari opo iroyin nipa majele eja ninu adagun na. Oro kan lati enu Alase Ile Ise Ijoba fun Ise Ogbin, Idagbasoke Ohun Osin ati Oro Iseda Aye so wipe igbese na waye lati fi dabobo awon olura, pelu awon aririnajoafe, ati oro aje erekusu na.

Ogagun Adam Nwakajuki so wipe bi otileje pe won ko iti mo pato boya awon eja adagun Victoria ti gboro lati ara oogun ipakokoropaeku, erekusu Zanzibar ko le sora re di akitan fun awon ounje ti won ti ko sile nibomiran. Igbesele na ti o tun kan eja lati inu odo Nile waye leyin igasoke ninu ikowole awon eja epiya ati eya miran. Ijoba ti fi awon oluyewo si awon ebute, idiko baalu, ile itura ati ile itaja nlanla ni erekusu na lati dena awon eja odo lati inu Adagun Victoria ati Odo Nile.

Oga agba kan ninu Ajo Erekusu Zanzibar fun Irinajo Igbafe, so wipe ile itura ti won ba ri ti o npese ounje ti won ti gbesele wa ninu ewu ipadanu iwe ase re.

I joba Erekusu na so fun awon ile itura to ba si ni epiya ni ipamo ki won ko won danu. Igbese lati dena ikowole eja odo lati oke odo orile-ede Tanzania, Kenya ati Uganda waye leyin ose meta pere ti Zanzibar gbesele tita orisi omi aladun kan ti won npe ni “Masafi” eyiti won nse ni ilu Dar es Salam. Ijoba erekusu na so wipe awon ayewo ti ile ise Oga awon Apoogun ti Zanzibar se ti “fihan” wipe omi “Masafi” ko dara fun mimu eniyan.

*Africa News On Line*

**Nwon ti si aso loju eto lati dabobo awon odo Ile Europe 1min 11secs**

Igbese akin kan lati dabobo awon odo ‘adayeba’ ti ile alawo funfun Europe yio bere losu yi, osu kesan odun 1999. Igbese na ti a pe ni ‘Awon Odo to wa Laaye’ je ipolongo jakejado ile na lati owo Ajo Akojo Owo fun Iseda Aye (Worldwide Fund for Nature (WWF) ajo kariaye fun itoju iseda aye. Ipolongo na ni a se lati se irusoke imo lori iwulo ati ise awon ilana odo adayeba, ki won se afihan awon irokeke ewu to ro mo ilokulo ati isakoso ti ko dara, ki won si se afihan ipa ti olukuluku ati awon ajo gbogbo ni ninu itoju omi mimo.

Gegebi WWF ti so, iponlongo na yio 'se agbekale ilana eto fun isakoso awon odo ni ile Europe ati fun iyipada ninu ofin'. Ipolongo na ni a o fi lole ni ilu Brussels ni ojo kokanlelogun osu kesan odun yi. Ni bayi iwe alaye kan oloju ewe ogun ni won o gbejade ni ipari osu kejo pelu akole 'Awon Odo Ile Europe to wa Laaye – Eto Fun Ise Sise'.

Gegebi WWF se so: "Eto fun Ise Sise" na yio ta Ajo Apapo ile Europe, awon ijoba orile-ede ati ti ibile, oko owo ati awon ile ise, awon to nse ipese omi ati awon egbe miran ti oro na kan laya lati fi ipinnu won han ki won si se awon ohun to baye"

*WWF*

**Opo awon obirin orile-ede Sudan lo wa logba ewon 1min 53secs**

O ju egberun lona ogbon awon obirin to wa lewon ni iha ariwa orile-ede Sudan to wa labe esin imale nitori awon ese kekeke. Eyi ju ida kan ninu ogorun gbogbo obinrin orile ede na lo.

Iko marundinlogorun ninu ogorun awon obirin na lo nsewon nitori pe won pon won si nta oti lile, gbogbo won lo si fere wa lati iha gusu Sudan nibiti pipon ati tita awon oti lile ki ise ese.

Gegebi iroyin laipe yi, o ju idaji ninu awon obirin na lo ti won tun nmu ti won si ndapada sewon leyin ti won ba ti fi won sile.

Iroyin na so bayi: "Awon irin-ise ipon-oti na ni won nta ninu oja gbanjo ita gbangba, eni mimo lo si nraa. Awon obirin yio fi ewon sile, won a tun lo ra irin ise ti won fi nro ti won si fi npon oti won a si tun beresi se owo kansoso ti won mo"

Nwon le mu obinrin, ki won gbe si ile ejo ki won si ju sewon laarin wakati mejidinladota, won a si ko irin ise re won a taa. Igba pupo ni won ma nse ejo won laisi agbejoro fun won. Lara ijiya won ni nina legba, owo itanran ati gbigbejusewon ti ko din ni osu mefa.

Opolopo ninu awon obirin na lo loyun sinu tabi to nto omo lowo. O ju ogorun omo lo ti won nbi ninu okan ninu awon ogba ewon na. Ninu omiran ninu won o ju igba awon omode ti won ti sewon pelu awon iya won nigba kan. Biotilejepe eka ti ogba ewon ni orile-ede Sudan ni a so wipe o wa ninu awon ti isakoso re dara julo ni ile Afirika, ikepe ti nwa fun awon ayipada lati se atunse awon ifiyajeni to buru to nsele si awon obinrin iha gusu ni iha ariwa nitori owo won ninu oti lile.

*Newslink Africa*

**Egbogi titun ndabobo awon omo ikoko awon iya to ni arun kogboogun AIDS** **1min 32secs**

O seese ki egbogi titun kan pese abo to daju to ko si nani lowo pupo fun awon omo ikoko ti awon iya to ni kokoro arun HIV to nyorisi arun kogboogun AIDS – Igbasara Isele Aikunojuwon Ajesara (Acquired Immune Deficiency Syndrome) gegebi iwadi alajosepo kan laarin orile-ede Uganda ati Amerika ti gbe jade laipe yi ni ilu Kampala ati Washington.

Awon abajade ti a koko mo lati inu asewo olodun-meji lori egbogi na fihan wipe idena ifunnini kokoro arun HIV sele nigbati won fun alaboyun to ni kokoro-arun HIV ni egbogi na ti a mo si Nevirapine (NVP) ni akoko to ba nrobi lowo, ti a si fun ikoko to bi ni egbogi na laarin ojo meta ti a bi.

Ifunnini arun dinku si idaji nigbati a se afiwe pelu itoju iru re pelu egbogi miran ti a mo si AZT eyi ti o le na eniyan lowo ni ilopo adorin sii, gegebi Ile ise Ijoba orile-ede Amerika fun Itoju Eda Eniyan ati Ilera se so.

Gegebi oro lati enu Dokita Anthony S. Fauci ti Ajo orile-ede fun Aibaramu ati awon Arun to nran eniyan to se onigbowo iwadi na: "Iwadi yi lo je eyiti o mu iwuri julo wa titi di isisiyi lori ifokansi wiwa awon ogbon imulo ti a le lo jakejado aye to dena itankale kokoro arun HIV lati odo awon iya si awon omo ikoko won"

Awon abajade na ni won gbe oriyin fun ninu ikede kan ni ilu Kampala: "Iwadi yi funni ni ireti gidi wipe o le seese fun wa lati dabobo opo ninu iran omo ile Afirika to mbo kuro lowo ibaje arun kogboogun AIDS" Eyi ni oro Crispus Kiyonga to je Alakoso fun Oro Ilera ninu ijoba orile-ede Uganda.

*Newslink Africa*

## Awon Apileko Oro

**Iha gusu ile Afirika dojuko Ewu Ajalu Ojiji lori arun kogboogun AIDS** **1min 45secs**

Arun kogboogun AIDS ti nbureke koja ohun ti apa le ka lo ni iha gusu ile Afirika lori gbogbo itiraka awon ijoba, awon ajo ti ko lowo ijoba ninu ati awon ajo ti agbegbe (community-based organizations (CBO) lati ru imo soke lori isoro kariaye na.

Awon akosile aipe yi fihan wipe awon orile-ede Botswana, Namibia, Swaziland ati Zimbabwe ni arun na kolu pupojulo ni iha gusu ile Afirika. O fere to idamerin awon olughe orile-ede wonyi ti o ni kokoro-arun HIV tabi arun kogboogun AIDS gangan. O fere to idamerin awon eniyan ti ojo ori won wa laarin odun medogun si mokandiladota to ni ikolu na.

Gegebi iwe iroyin olosose ti orile-ede Amerika ti a mo si TIME se so, Ile-ise Ilera ti orile-ede South Africa siro wipe kokoro arun na yio kolu o kere tan idamarun awon osise ni odun to nbo. Laarin odun meta si, awon ti yio ku yio to egbegberun lona adotalerugba ti won yio si fi awon omo orukan to to ogbon oke sile. Ati siro wipe arun na yio ge ogun odun kuro ninu iwontunwonsi igbe aye, yio si mu ilosiwaju oro aje joro pelu iko meji ninu ogorun.

Gegebi iroyin ajo UNDP lori idagbasoke eda eniyan fun odun 1998 se kilo: "Ajakale arun na yio ni ipa to le lori oro aje ayafi ti a ba se agbekale awon ilana ati eto lati koju awon ikolu re lori ipese osise ati ise sise.

Gegebi Alakoso Ijoba fun Ilera ni orile-ede South Africa, Nkosama Zuma se so, orile-ede na lo ni igasoke to po ju lo ninu awon alaisan kokoro arun HIV ti awon ti o si to oke meji abo eniyan ngba kokoro-arun na sara lososu. Awon wonyi je isiro to lewu gidigidi. Won nfun wa ni ikilo pe ohun gbogbo ko lo dede ninu ija orile-ede na pelu ajakale arun AIDS na.

*Newslink Africa*

**Ile Afirika polongo awon Anfani Idoko-owo to wa ninu re 2min 45secs**

Gegebi ijoba oloselu ti nfesemule ni ile Afirika, awon oludoko-owo ni agbaye ti beresi fi okan si awon anfani idoko-owo to wa ni ile na. Besi ni fun ojo meji ninu osu kewa odun yi ni ilu Dakar, orile-ede Senegal, ile Afirika yio ni anfani lati gba gbogbo aye to ku lalejo ninu apero pataki kan lori idoko-owo lati fa awon alase ijoba to wa fun ifowosowopo lori idagbasoke lati ile alawo funfun Europe, awon logaloga pataki ninu awon ajo oloko-owo nlanla, awon olori ijoba ni Afirika ati awon alakoso ijoba fun oro isowo ati isuna owo.

Gegebi iroyin aipe yi kan lati owo ajo oniroyin, Newslink Africa, lara awon alejo lati awon orile-ede Europe ni ati ri arabinrin Clare Short, Alase ijoba orile-ede Geesi fun Idagbasoke Kariaye ati Ogbeni Paul Nielson, Alakoso ijoba orile ede Denmark fun Idagbasoke ati Ifowosowopo. Awon miran ni Ogbeni Kenzo Oshima, Oludari agba fun Ajo orile-ede Japan fun Ifowosowopo lori Oro Aje ati arabinrin Hilde F. Johnson, Alakoso Ijoba orile-ede Norway fun Idagbasoke Kariaye ati Eto Eda Eniyan.

Arabinrin Evelyn Herfkens to je Alakoso Ijoba orile-ede Netherlands fun Ifowosowopo lori Idagbasoke na yio pese pelu awon osise ijoba agbaagba lati orile-ede Faranse, Germany, Finland ati Itali.

Awon to jumo se agbekale apero nla na ni Ajo Apapo orile-ede Agbaye fun Idagbasoke Oko-owo (United Nations Industrial Development Organization (UNIDO), Ajo Alasepo fun Itesiwaju Isowo ni ile Afirika (Alliance for Africa's Industrialization), Ajo Oro Aje fun ile Afirika (Economic Commission for Africa), Banki Idagbasoke ile Afirika (African Development Bank (ADB) ati Ajo Isokan fun ile Afirika (Organization for African Unity (OAU).

Lara awon oro ti won yio so ni a o ti ri ikolu ti ilujarawon aye ni lori idagbasoke isowo ni ile Afirika, oju-ojo fun idoko-owo ni ile na, imuwonuarawon nipa oro aje ni elekun-jekun, ifowosowopo laarin ile Europe ati Afirika ati idagbasoke agbara awon aladani. Ona igbeowosile fun awon ise kereje-kereje na ni won o tun jiroro lori re.

Ipade osu kewa na je abajade ipolongo OAU ni ilu Harare ni osu kefa odun 1997. O fi ase fun akowe-agba ti ECA lati seto ipade awon orile-ede ati ajo to ngbe-owo sile pelu ile Afirika lati wa ona fun inawo fun ilana ise fun idagbasoke ile Afirika.

Awon olugbowo ipade na lero wipe yio jeki eto idagbasoke isowo ni ile Afirika yara si ki awon orile-ede Afirika le ni awon alabasisepo titun laarin ile na ati ni agbaye. Iroyin lati ajo Newslink Africa na so bayi: "Ifowosowopo nipa ise ona se pataki fun imudarasi ayika fun idoko-owo aladani ni opolopo orile ede, o tun ma nse iranwo lati se agbedide awon onisowo omo ibile to lagbara to si le ni ifowosowopo to lagbara pelu awon oloko owo lati eyin odi won"

*Newslink Africa*

**Opo Iresi sii pelu Omi ti ko to ti tele** **2mins 34secs**

O seese ki iwadi onikiakia fun awon ona titun lati fi gbin iresi pelu omi ti ko to ti tele ri ti bere si mu eso rere jade. Won ti se agbedide awon ona titun lati fi gbin iresi. Awon ona na ti a pe ni irugbin ni tutu, ifomirin iresi lorekore, imuleteju, isakoso epo to darasi ati isakoso awon ile to san, ni egbe olujodamoran kan lori Iwadi Ise Ogbin ni Kariaye ti a mo si CGIAR se agbedide re lati din ikolu nla lori ipese omi ti ibere giga si fun iresi mu wa ku.

Awon ona titun yi se igbelaruge idinku ninu omi lilo fun ire iresi to ga si ni sare ile hektari kokan. Alaye lori bi won se nsise ni a ko menuba ninu iroyin CGIAR na sugbon sa, Ismail Serageldin to je alaga CGIAR ati Adele Aaare Banki Agbaye to wa fun awon Eto Pataki so wipe iresi ma nnilo omi to to ilopo meji ti irugbin oka miran ati pe o ju egbaa kan iwon tonnu omi kan lo ti won nlo lati fi gbin iwon tonnu iresi kan. Eyi ko ni seese mo bi ipese omi mimo ni agbaye ba se nyara din ku ti ibere fun iresi ni agbaye si npo si.

Ni ogbon odun sii, yio ju idaji awon olugbe aye lo ti yio gbarale iresi gegebi ogunna gbongbo orisun ounje won. Awon agbegbe ibile fun ogbin iresi ni iha ariwa ati gusu orile ede Naijiria ni o wa labe irokeke ewu nla lati inu kiko ibi iwojopo agbami nla, igasoke iyo inu ile ati igberu si awon ilu. Gegebi oro Ronald Cautrell, Oludari agba fun Ile Ise Kariaye fun Iwadi lori Iresi, to je ibudo CGIAR ni orile-ede Philippines: "Pelu ipadanu ile to wa fun ogbin iresi latari igberu awon ilu, ibaje ile ati igasoke iyo inu ile, isoro na di ti igberusi ire ninu awon ipo to nganilara si"

Awon ona titun na le se iranwo lati gbe awon oro aje awon orile-ede to sese ndagbasoke ro. Opo ninu awon orile-ede to nsogbin iresi julo wa lara awon orile-ede to sese ndagbasoke, eyiti Banki Agbaye pe ni "awon oro aje ti owo to nwole lo sile pupo" Ile Asia nikan ni metadinlogun ninu awon orile ede medogbon to je ogbontarigi ninu ogbin iresi. Awon ni won nse ogbin ninu iko adorun ninu ogorun gbogbo ile ogbin iresi jakejado aye, awon na ni won si nse ipese iko adorun ninu ogorun gbogbo ipese iresi ni agbaye. Nitoto, idameta gbogbo ile ogbin ni opo ninu awon orile ede ologbin iresi ni ile Asia ni o je wipe iresi ni won ngbin sori ile won.

*CGIAR*

**Awon oko inu ofurufu ayiayepo le sotele lori ibesile iba oloro 2mins 7secs**

Ibesile buruku ti kokoro arun Iba Afonifoji Rift to pa opolopo maalu run ni iha ila oorun Afirika ti o si ni abajade to buru jai fun awon eniyan ni a le se idena re. Awon iwadi titun ti fihan wipe ibesile iba na ni akoko ati igba tire. Akoko isele yi ni a ti le motele fun bi osu mefa saaju nipa lilo awon oko inu ofurufu ayiayepo ti iwo oju ojo ki a si gbe igbese lati pa awon ohun to le fa run.

Eyi lo waye latari iwadi titun ni ibudo Ifo ninu Ofurufu ti NASA to wa ni Goddard ati ti Eka Idabobo Ilana Arun to nran ni ni Agbaye (Department of Defence Global Disease Infections System) ni Ile Ise Iwadi Ologun ti Walter Reed in ilu Washington D.C, orile-ede Amerika.

Awon oluwadi ri wipe ibesile arun na ma nsaba se pekireki pelu awon akoko ojo pupo to tan ka agbegbe to po ni ila oorun Afirika. Won se ayewo akosile nipa oju ojo fun adota odun won si ri daju wipe ibesile arun na meji lo sele laarin odun metadinlogun to koja to si se pekireki pelu akoko opo ojo. Kokoro arun na di awati laarin awon ibesile na.

Gegebi awon abajade iwadi, efon ti a mo si Aedes lo ngbe kokoro arun na wonu eyin re, eyiti a npa ninu ile tutu leyin ti ogbara bati ti wo lo. Awon efon kekeke na a ma je awon eran osin. Ilana yi ma ntesiwaju laisi isele kokan titi di igba ti awon efon ti a mo si Culex ba wole de. Awon efon Culex lo nfa awon ibesile nla nigbati won ba ti je awon eran osin to ti ni kokoro arun na lara. Efon Culex yi ke, akoko opolopo ojo nikan ni won npo si.

Awon oluwadi so wipe awon akosile oko inu ofurufu ayiayepo le sotele nipa ibesile Iba Afonofoji Rift nibi osu mefa saaju akoko na ti yio sele. Gegebi oro Compton Tucker, amoye Goddard kan lori imo nipa eya ara ati idagbasoke eweko ati eranko to ti lo akosile oko inu ofurufu ayiayepo lati fi woye eweko ni ile Afirika fun odun to le ni ogun so wipe "Ohun ti o dunmo mi nibiyi ni wipe akosile oko inu ofurufu le fun wa ni ikilo saaju nipa awon ohun to sedede pelu ibesile Iba Afonifoji Rift ki o si wa se afihan agbegbe ti oro na kan gan"

*Environmental News Network*

# Eto Awon Omode

**Kiniun ati Eku** **2min 3secs**

Kiniun ni gbogbo eniyan mo si oba awon eranko nitori o lagbara pupo o si le 'fiyaje' eranko keranko pelu agbara nla re. Nitorina gbogbo eranko lo beru ti won si bowo fun kiniun. Won a si ma se ohun gbogbo to wa nipa won lati ma bo si owo ibinu re. Gbogbo eranko lo nsapa won lati ri ojurere kiniun ki won si je ore re.

Ni ojo kan, kiniun wa loju orun nigbati eku sesi sare koja lori inu re. Kiniun ti o ji pelu ibinu, mu eku o si fe pa nigbati eku bebe 'Jowo ma pa mi. Boya ni ojo kan emi na le gba emi oba eranko la' Erin pa kiniun nighati o ronu lori wipe eku 'kekere' fe gba emi on, kiniun, oba ati eranko to lagbara ju la.

Sugbon sa, kiniun fi eku sile pelu ikilo wipe ko mase di orun on lowo mo. Eku dupe lowo kiniun o si lo sile. Ko pe leyin eyi nigbati kiniun nri kiri inu igbo ti o bo sinu awon ti awon ode de. Nigbati o kigbe fun iranlowo gbogbo awon eranko to ku ko daa lohun nitori won beru wipe yio pa awon je ti awon ba tu sile. Nigbatoya, eku gbo igbe kiniun o si wa ranti wipe nigbakan ri, kiniun da emi on si. O pinnu lati san ore na pada nipa dida kiniun sile. Nigbati o nsunmo kiniun o ri wipe awon okun aso oniyoloyolo ti won hun papo ni won fi se awon na. Eku bere ise o si bere si fi ehin ge awon okun aso oniyoloyolo na titi ti o fi se iho nla to gba kiniun lati jade.

Nigbati o ti da kiniun sile eku so wipe "nigbati o da emi mi si, o rerin nigbati mo bebe wipe emi na le gba emi oba awon eranko la"
Eni ba dami siwaju, yio tele tutu.
*Character Moulding Stories for Better Citizenship.*

**Kini idi re ti awon Adan fi nfo lale?** **1min 5secs.**

Awon adan je eran oru ti ko ni ona lati fi dabobo ara won. Okunkun ni aabo won. Ota won to buru julo ni eye kan ti a npe ni asa adan, eyiti o ma nsode ni irole-mo-ale nigbati awon adan ma nfi ibugbe won ninu iho ati ori igi sile. Awon eya die ma nje awon kokoro oru bi afopina. Awon omiran, gegebi adan eleso, a ma je eso igi to ba pon ni ale nigbati enikeni ko le ri won. Nitorina awon adan ma nfo ni ale nitoripe ko si ewu ati pe ounje won rorun lati ri.

Ninu gbogbo eranko to wa laye, adan nikan ni eyi to le fo. Awon iye won ni a se pelu tanna awo to na lati aarin awon ika eegun owo won to gun si egbe won ati ese eyin won. Awon eniyan die ro wipe afoju ni awon adan. Eyi ko ri be. Gbogbo adan lo ni oju won si le riran daadaa lale.
*Chongololo*

**Iwa odaran lo buru jai ti Ehoro to nje Kadima ni 4mins 10secs**

Nigbakan ri, gegebi awon eniyan to je eya Hambakush ti iha gusu ile Afirika se so, ehoro to nje Kadima ni adehun pelu amotekun to nje Nthoo lati ma so awon ikoko amotekun na meta nigbati o ba ti jade lo sode. A si ma fun Kadima lara awon ohun ode re fun ounje ale. Eto irorun yi sise daada titi di igbati ogbele lile kan de si ile na. Gbogbo awon eranko egan ti Nthoo ma nsode re ti si lo lati wa omi lo si awon ekun miran, nkan si wa le fun amotekun na, awon omo re ati Kadima. Lojojumo ni Nthoo npada wale lairi ounje mubo. Laipe, ebi bere si pa won.

Ni ojo kan, Nthoo pada wale o si ba Kadima to njeun. Nigbati o si bi lere bawo ni o se ri ounje nigbati on to je ode to dara julo ni gbogbo ile na ko ri ohukohun, Kadima dahun wipe ekulu kekere kan ni o koja lenu iho na on dogbon mu on si paa. Sugbon otito oro na ni wipe eran ti Kadima nje je okan ninu awon omo amotekun na!

Ni ojo keji, Nthoo tun sode lo, Kadima ika si tun pa omiran ninu awon omo re o si jee. Nigbati amotekun tun pada lowo ofo ni irole ojo yen, o dubule taaretaare o si wa so fun Kadima ki o gbe awon omo oun wa ki on toju won. Kadima ologbon ewe gbe omo kansoso to ku wa lemeta sodo Nthoo o si wa tan lati gbagbo wipe awon omo re wa laaye ati lalafia.

Ni owuro ojo keji, leyin ti Nthoo ti lo, ebi pa Kadima tobe ti o tun fi pa omo amotekun kansoso ti o ku to si jee. Lati bo ese re mole o fi awon aami iro si ati wole ati ati jade kuro ni iho na, o si wa tu ile ka, o se opolopo eka igi lati jeki o dabi enipe ija nla sele nibe.

Leyin na o lo sibi iho omi to ti gbe o wa kun ara re ni pupa pelu efun pupa. Nigbati Nthoo pada wale, Kadima to ri bi alaisan lo ba, o nsunkun, o si so fun wipe awon eniyan ti pa awon omo re won si ti gbe won lo je. On gbiyanju lati dabobo won sugbon awon ode na lu on pupo on si ti fere ku latari eje ti on padanu. O si wa toka si awon epon to wa lori irun ara re. O ma se o fun Nthoo! Ninu ibinu nla o gberaso lati lo si abule to sunmo ibe pelu ipinu lati gbesan lara awon eniyan to pa awon omo oun je.

Sugbon sa, bi amotekun na ti fe be le awon egbe odomokunrin kan ni oko na, ohun nla kan kigbe lati ori igi wa “Nthoo!” ohun na nje ti olofofo igbo ti a mo si ‘Eye ma lo’. ‘Nthoo’ o tun kigbe. Kadima ni ika na to pa awon omo re, kii se awon eniyan daradara abule naa!”

Nthoo yipada ni ibinu lati lo wa Kadima sugbon Kadima ti gbo eye na, o si ti salo pelu iberu nla. Amotekun na, Nthoo, ko tii ri Kadima, ehoro, mu sugbon awon eniyan Hambakush wipe wiwa kiri na si ntesiwaju sibe. Nitori eyi ni amotekun se nrora ti o si ma ndanikan sode. Idi tun ni yi ti ehoro fi ma nsalo lai bojuwehin ti ohunkohun ba sesi deba lojiji.
*When Hippo Was Hairy*

**Alafo laarin iforukosile okunrin ati obirin ni ile-eko ni ile Afirika Awon otito to wulo ni arowoto 46secs**
Opo awon omokunrin ni a nfi oruko won sile ju awon omobirin lo ni ile eko akobere ati girama ni opolopo orile-ede Afirika. Iyosirawon iforukosile je omokunrin meji si omobirin kan ni awon orile ede mokanla lara eyiti a ti ri Naijiria, Ghana, Cote d'Ivoire, Republic of Benin ati Democratic Republic of Congo. Eyi ni gegebi awon akosile ti Ajo Gbogbo Orile Ede Agbaye gbe jade laipe yi. O ju awon orile-ede mejidinlogun lo to ni alafo to mo niwon lara awon ti a ti ri orile ede Egypt, Zimbabwe, Uganda, Ethiopia, Cameroun ati Algeria. Awon orile ede meje ko ni alafo ti eyameya nigbati orile ede South Afirika ati Lesotho ni alafo ti idakeji ti iye awon obirin to ju awon okunrin lo die foruko sile ni ile eko akobere at girama
*United Nations*

**Idaamu lori Omi Mimo 14secs**
Awon orile ede mokanlelogbon lo wa jakejado aye nisisiyi ti won ni idojuko owongogo omi. Nigbati yio ba fi di odun 2025, iye won ni a fokansi wipe yio ti lesi di mejidinladota nigbati yio de gongo ni marundinlogota ni odun 2050.
*CGIAR*

**Orile Itali gboro nipa iwa odaran lori ayika 44secs**
Leyin ti a ti ni akosile ogogun idanasun lojojumo ninu awon ogba egan orile ede re, orile ede Itali ti seleri owo italore to fere to oke meta owo dola Amerika lori awon adanasugbo. Ebun na ni a o fun oluranlowo nigbati a ba mu odaran na de ile ejo.

Awon iroyin so wipe ina ti awon adanasungbo nda lododun nfa ibaje to ga ninu awon igi ati igbo orile ede Itali. Iroyin WWF – Ajo Akojo Owo ni Agbaye fun Iseda Aye (WorldWide Fund for Nature) so wipe "o fere to ina mejidinlogbon ti won nroyin re lojojumo ni akoko ooru ni odun marun to koja, gbogbo ibiti won si dana sun je oke metadinlogun sare hektari. Opolopo ninu won lo si je lati owo awon adanasungbo".
*WWF*

**Isaretobisi awon ilu ntesiwaju ni ile Afirika 21secs**

Opolopo eniyan ni ile Afirika lo nfi aroko sile lati lo tedo si arin ilu ju ni awon ibomiran ni aye. Laarin odun 1995 ati 2025, a siro wipe iye awon olugbe ilu yio di ilopo meji jakejado aye. Sugbon ni ile Afirika, awon olugbe ilu yio di ilopo meta ni akoko kanna.

*Boiling Reint*

**Eye to nso agogo 59secs**

Nje o ti gbo eye to nso akoko ti ojo je fun o? Ni orile ede Indonesia awon oluwadi to nse ayewo iwa eya eye kan ti a pe ni Pitta Erythro*gaster* ti se awari ohun kan to yanilenu. Won ri wipe eya alaya pupa na ni ona to yato to ma fi nmo akoko lojojumo. Ni kutukutu, eye na o wa lori ile, yio ma korin owuro re. Bi oorun ba se yo yio gun igi titi yio fi de tente re nigbati ojo ba kanri. Nigbana, ti oorun ba ti nlo sile, eye na yio sokale igi na lati eka si eka, yio si pada si ile ati ite re bi oorun ba se nwo ni agogo mefa irole. Ko tan sibe o. O le so wipe ojo yio ro ni ojo yen ti eye na ba duro sori ile ni gbogbo ojo na

*WWF*

**Oro ti enikan so lori: Itoju Ipadanu Ipinsiyeleyele**
**Eweko ati Eranko 34secs**

"Ohun to buru julo to le sele… ki ise idinku nkan agbara, iwopale oro aje, ija olun-ose apayerun nuclear die, tabi imunileru. Bi awon ajalu yi yio ti buru to fun wa, a le se atunse won laarin iran bi melo kan. Ilana kan to nlo lati bi ogun odun seyin ti yio gba wa ni egberun odun lati tunse ni ipadanu ipinsiyeleyele iru ati eya ati iparun awon ibugbe adayeba. Eyi ni asise wa ti awon iran to nbo leyin wa ki yio le dari re ji wa

*Edward o.Wilson, Ojogbon ni Yunifasiti Harvard*

**Orile-ede Canada se pataki si ipinsiyeleye awon eweko**
**ati eranko 26secs**

Orile-ede Canada lo ni idamewa ninu gbogbo igbo agbaye, agbegbe to to okolenirinwodinmeji milionu sare hekitari, to fere bo idaji orile ede na. Awon igbo lo nse iranwo lati se agbero idamarun gbogbo omi mimo to walaye ki o si pese ibugbe fun awon eya eda abemi egan to to oke meje. Orile ede na ni o nfi ire igbo to poju lagbaye gegebi igi gedu ranse si ile okeere

*WWF*

# Awon Ageso Oruko

| | | |
|---|---|---|
| AAI | - | Ajo Alasepo fun Itesiwaju Isowo ni Ile Afirika |
| ADB | - | Banki Ile Afirika fun Idagbasoke |
| AIDS | - | Igbasara Isele Aikunojuiwon Ajesara inu Ara |
| CGIAR | - | Egbe Olujodamoran Lori Iwadi Ise Ogbin ni Kariaye |
| ECA | - | Ajo Oro Aje fun Ile Afirika |
| FAO | - | Ajo Agbaye fun Oro Ounje ati Ise-Ogbin |
| HIV | - | Kokoro Arun to nfa Aikunojuiwon Ajesara ninu Eda Eniyan |
| NCF | - | Ajo Afenifere fun Itoju Ayika ati Iseda Aye ni Orile-ede Naijiria |
| NGO | - | Ajo ti ko ni owo Ijoba ninu |
| OAU | - | Ajo Isokan ile Afirika |
| UN | - | Ajo Apapo awon Orile ede Agbaye |
| UNDP | - | Ajo Apapo awon Orile ede Agbaye fun Eto Idagbasoke |
| UNIDO | - | Ajo Apapo awon Orile-ede Agbaye fun Idagbasoke Isowo |
| UNITA | - | Egbe Ajumose fun Ominira Patapata fun orile ede Angola |